*Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krístì, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àinípẹ̀kun. Àmín.*

Tí o bá gba àdúrà yìí látọkànwá, a bá ọ yọ̀, nítorí o ti di ọmọ Ọlọ́run báyìí (Jòhánù 1:12-13).

### Kíló kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ tí o ti lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!

*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

**DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL**
*~ À ń tan Ìhìnrere Káàkiri Aiyé*

**www.divineliterature.org**
**www.doveletters.org**

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023

# Aṣẹ́gun kìí Jáwọ́

*...O ti Fẹ́rẹ̀ẹ́ Débẹ̀*

Ǹjẹ́ o ti gbọ́ nípa Ìhìnrere Ìgbàlà tàbí Orúkọ tí a mọ̀ ní JÉSÙ, ṣùgbọ́n o ti rò wípé ìkà ènìyàn tí kò yẹ láti rí ìdáríjì gbà, ni ọ́? Ṣé o ti yàn láti máa bá ìgbésí aiyé rẹ lọ bí ó ti burú tó, nítorí o ti gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé kò sí ìdáríjì fún *"ẹ̀ṣẹ̀ ńlá"* rẹ, tàbí àwọn *"ẹ̀ṣẹ̀ rẹ tí ó pọ̀ jù láti kà"*? Ṣé ò ń kọ̀rìíra ara rẹ nígbàmíràn, débi pé ò ń gbèrò láti fi aiyé sílẹ̀? Bóyá ìdí tí o fí ń lọ́ra láti fi aiyé rẹ fún Jésù Krístì ni pé, àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ ń tì ọ́ lójú, o sì rò pé o ní láti ṣe ìjẹ́wọ́ wọn fún olùṣọ́ kan, olùdámọ̀ràn, tàbí ọ̀rẹ́

*Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krístì, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àinípẹ̀kun. Àmín.*

Tí o bá gba àdúrà yìí látọkànwá, a bá ọ yọ̀, nítorí o ti di ọmọ Ọlọ́run báyìí (Jòhánù 1:12-13).

Kíló kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ tí o ti lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!

*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL
~ À ń tan Ìhìnrere Káàkiri Aiyé

www.divineliterature.org
www.doveletters.org

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023

Aṣẹ́gun kìí Jáwọ́

...O ti Fẹ́rẹ̀ẹ́ Débẹ̀

Ǹjẹ́ o ti gbọ́ nípa Ìhìnrere Ìgbàlà tàbí Orúkọ tí a mọ̀ ní JÉSÙ, ṣùgbọ́n o ti rò wípé ìkà ènìyàn tí kò yẹ láti rí ìdáríjì gbà, ni ọ́? Ṣé o ti yàn láti máa bá ìgbésí aiyé rẹ lọ bí ó ti burú tó, nítorí o ti gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé kò sí ìdáríjì fún "ẹ̀ṣẹ̀ ńlá" rẹ, tàbí àwọn "ẹ̀ṣẹ̀ rẹ tí ó pọ̀ jù láti kà"? Ṣé ò ń kọ̀rìíra ara rẹ nígbàmíràn, débi pé ò ń gbèrò láti fi aiyé sílẹ̀? Bóyá ìdí tí o fí ń lọ́ra láti fi aiyé rẹ fún Jésù Krístì ni pé, àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ ń tì ọ́ lójú, o sì rò pé o ní láti ṣe ìjẹ́wọ́ wọn fún olùṣọ́ kan, olùdámọ̀ràn, tàbí ọ̀rẹ́

tí ó lè kọ̀ é, fi é ṣèsín, tàbí kí ó táṣìírí ohun tí o ba sọ níkọ̀kọ̀ lọ́jọ́ iwájú.

Má ṣe jẹ́ kí ẹnikẹ́ni ṣì é lọ́nà! Ẹ̀jẹ Jésù ń wẹ̀ wá mọ́ kúrò nínú gbogbo onírúurú ẹ̀ṣẹ̀ (1 Jòhánù 1: 7). Láfikún, kì í ṣe dandan kí o jẹ́wọ́ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ fún ènìyàn láti ní ìgbàlà. Kò sí ẹnì kan láiyé tó ní agbára láti gbà ọ́ là. Jésù Krístì nìkan ló ń gba ènìyàn là. Òun nìkan ṣoṣo ni Alárinà láàárín àwa àti Ọlọ́run Baba (1 Tímótì 2:5); kò sí ẹlòmíràn tó ní àṣẹ yìí. Sísọ ẹ̀dùn ọkàn rẹ fún àwọn tí wọ́n lè fún ọ ní ìmọ̀ràn oníwà-bí-Ọlọ́run jẹ́ ohun tó dára lóòótọ́. Àmọ́, ìyàtọ̀ wà láàárín kí o máa wá àtìlẹ́yìn àwọn ènìyàn láti borí àwọn àìlera tí o ní, àti kí o máa jẹ́wọ́ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ fún wọn láti ní ìrẹ́pọ̀ pẹ̀lú Ọlọ́run kí o lè rí ìdáríjì Rẹ̀ gbà. Lẹ́yìn tí a bá jọ̀wọ́ aiyé wá fún Jésù Krístì ni à ń rí ìdáríjì Ọlọ́run gbà, tí a ó sì jẹ́ olódodo ní oju Rẹ̀.

Àìṣètọ́ tí ó burú jùlọ tí o lè ṣe sí ara rẹ ni, kí o pinnu láti jìnnà sí Ọlọ́run nítorí ẹ̀ṣẹ̀ rẹ - nírònú pé, oore-ọ̀fẹ́ Rẹ̀ kò tọ́ sí ọ. O di aṣẹ́gun nígbà tí o gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ tí o nílò ìràpadà ni ọ́; pé o sì ń fẹ́ ìdáríjì Ọlọ́run, ayọ̀ tí kò lópin, àti àlàáfíà tí yóò pẹ́ títí. Má ṣe rò ó láti sún Ọjọ́ Ìgbàlà rẹ síwájú, kí o gba Sátánì láyè láti jèrè ìṣẹ́gun mìíràn nínú ìgbésí aiyé rẹ. Kò sí ẹ̀dá alààyè kan tí ó ṣèèṣì wà lórí ilẹ̀-aiyé. Ọlọ́run ní àwọn ètò ńlá fún ọ: Ó fẹ́ rí i pé o ṣe àwọn ohun dára-dára tí Ó dá ọ sáiyé láti ṣe. (Gẹ́nẹ́sìsì 1:26-28, Éfésù 2:10). Kì í ṣe ohun tí ó le rárá, bóo ṣe rò, láti jọ̀wọ́ aiyé rẹ fún Krístì. Ṣe ìpinnu tí yóò mú ìyípadà wá sí ìgbésí aiyé rẹ lónìí. Má ṣe dẹ́kun láti jọ̀wọ́ aiyé rẹ fún un. Tẹ̀ síwájú, kí o bori!

## Báwo ni a ṣe lè gba Jésù Krístì nísinsìnyí?

Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Romu 10:9).

1. Gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́.
2. Ṣe ìpinnu láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.
3. Gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Jésù Krístì kú fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ lórí àgbélébùú, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú.
4. Lẹ́yìn náà, tẹ orí rẹ ba, kí o gba àdúrà yìí:

*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n: Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jíǹde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti*

tí ó lè kọ̀ é, fi é ṣèsín, tàbí kí ó táṣìírí ohun tí o ba sọ níkọ̀kọ̀ lọ́jọ́ iwájú.

Má ṣe jẹ́ kí ẹnikẹ́ni ṣì é lọ́nà! Ẹ̀jẹ Jésù ń wẹ̀ wá mọ́ kúrò nínú gbogbo onírúurú ẹ̀ṣẹ̀ (1 Jòhánù 1: 7). Láfikún, kì í ṣe dandan kí o jẹ́wọ́ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ fún ènìyàn láti ní ìgbàlà. Kò sí ẹnì kan láiyé tó ní agbára láti gbà ọ́ là. Jésù Krístì nìkan ló ń gba ènìyàn là. Òun nìkan ṣoṣo ni Alárinà láàárín àwa àti Ọlọ́run Baba (1 Tímótì 2:5); kò sí ẹlòmíràn tó ní àṣẹ yìí. Sísọ ẹ̀dùn ọkàn rẹ fún àwọn tí wọ́n lè fún ọ ní ìmọ̀ràn oníwà-bí-Ọlọ́run jẹ́ ohun tó dára lóòótọ́. Àmọ́, ìyàtọ̀ wà láàárín kí o máa wá àtìlẹ́yìn àwọn ènìyàn láti borí àwọn àìlera tí o ní, àti kí o máa jẹ́wọ́ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ fún wọn láti ní ìrẹ́pọ̀ pẹ̀lú Ọlọ́run kí o lè rí ìdáríjì Rẹ̀ gbà. Lẹ́yìn tí a bá jọ̀wọ́ aiyé wá fún Jésù Krístì ni à ń rí ìdáríjì Ọlọ́run gbà, tí a ó sì jẹ́ olódodo ní oju Rẹ̀.

Àìṣètọ́ tí ó burú jùlọ tí o lè ṣe sí ara rẹ ni, kí o pinnu láti jìnnà sí Ọlọ́run nítorí ẹ̀ṣẹ̀ rẹ - nírònú pé, oore-ọ̀fẹ́ Rẹ̀ kò tọ́ sí ọ. O di aṣẹ́gun nígbà tí o gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ tí o nílò ìràpadà ni ọ́; pé o sì ń fẹ́ ìdáríjì Ọlọ́run, ayọ̀ tí kò lópin, àti àlàáfíà tí yóò pẹ́ títí. Má ṣe rò ó láti sún Ọjọ́ Ìgbàlà rẹ síwájú, kí o gba Sátánì láyè láti jèrè ìṣẹ́gun mìíràn nínú ìgbésí aiyé rẹ. Kò sí ẹ̀dá alààyè kan tí ó ṣèèṣì wà lórí ilẹ̀-aiyé. Ọlọ́run ní àwọn ètò ńlá fún ọ: Ó fẹ́ rí i pé o ṣe àwọn ohun dára-dára tí Ó dá ọ sáiyé láti ṣe. (Gẹ́nẹ́sìsì 1:26-28, Éfésù 2:10). Kì í ṣe ohun tí ó le rárá, bóo ṣe rò, láti jọ̀wọ́ aiyé rẹ fún Krístì. Ṣe ìpinnu tí yóò mú ìyípadà wá sí ìgbésí aiyé rẹ lónìí. Má ṣe dẹ́kun láti jọ̀wọ́ aiyé rẹ fún un. Tẹ̀ síwájú, kí o bori!

## Báwo ni a ṣe lè gba Jésù Krístì nísinsìnyí?

Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Romu 10:9).

1. Gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́.
2. Ṣe ìpinnu láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.
3. Gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Jésù Krístì kú fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ lórí àgbélébùú, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú.
4. Lẹ́yìn náà, tẹ orí rẹ ba, kí o gba àdúrà yìí:

*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n: Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbésí aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jíǹde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti*